NEW YORK STATE OF OPPORTUNITY. | Office of the Medicaid Inspector General

Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gá Àgbà ti Medicaid (OMIG) Ìpínlẹ̀ New York ń dá ààbò bo ṣíṣe ìwà òtítọ́ ti ètò Medicaid nípa dídènà àti rírí àwọn ìṣe ìtànjẹ, àṣìlò, àti ìfiṣòfò láàrín ìpínlẹ̀ náà ti ètò Medicaid àti ìgbàpadà àwọn owóa Medicaid tí a ná ní ìnákúnàá, nígbàtí a ń gbé ìtọ́jú dídára ti aláìsàn lékè.

Adarí tí a mọ̀ káàkiri orílẹ̀-èdè láàrín àwọn aṣojú ìwà òtítọ́ ti ètò Medicaid, OMIG ìgbìyànjú ìgbàpadà àti iye-owó àwọn ọgbọ́n-inú ìdádúró ti tọ́jú mílíọ̀nù lọ́nàá ọgọ́rùún dọ́là ti àwọn ti ń san owó -orí ní ọdún kọ̀ọ̀kan.

Àwọn olùgbé New York le ṣèrànwọ́ fún OMIG láti gbógun ti ìtànjẹ, ìfiṣòfò, àti àṣìlò nípa ìfisùn àwọn dókítà tí a furasí tàbí ìwà kan tí ko nílò. OMIG rọ ẹnikẹ́ni tó kíyèsí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìtànjẹ Medicaid tó le wáyé, ṣòfò, tàbí àṣìlò sí kàn sí OMIG. Àwọn ìtanilólonbó le jẹ́ aláìlórúkọ pátápátá—àti wípé OMIG yóò tọ́pinpin gbogbo àlàyé tí a fisùn.

Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gà Àgbà ti Medicaid
800 North Pearl Street
Albany, NY 12204
(518) 473-3782

Facebook and Twitter @nysomig

## Bí ìtànjẹ Medicaid ti ṣe kàn ọ́:



Ìtànjẹ Ìtọ́jú ìlera kììṣe ọ̀ràn tí kò ní ẹnití a dá lóró.

**Àwọn olùsan owó-orí:** Kódà ìṣirò tó kéré jù ti ìtànjẹ Ìtọ́jú ìlera ṣojú àpọ̀jù ọ̀fò lórí ìlànà ìtọ́jú ìlera ti àwọn ènìyàn. Àwọn olùsan owó-orí ní Ìpínlẹ̀ New York àti káàkiri orílẹ̀-èdè ń forí fáa.

**Àwọn olùgbà:** Nígbàtí olùpèsè kan bá parọ́ àwọn iwé-ẹ̀rí rẹ̀ àti àwọn ìṣẹ́, o le fi ìlera rẹ sábẹ́ ewu. Nípa píparẹ́ tàbí ṣe àsọdùn àyẹ̀wò àìsàn, tó le ṣàfikún àìsàn kan sí àkọsílẹ̀

ìtọ́jú ìlera rẹ èyítí o kò ní. O le wà lábẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ àwọn ìṣẹ́ ìlera tí kò ní ààbò, le gba ìtọ́jú ìlera tí kò yẹ, tàbí rìí wípé

àwọn ànfàní ìlera rẹ ti dópin.

**Àwọn olùpèsè:** Àwọn ìṣe ti ìwọ̀nba díẹ̀ olùpèsè tí ń ṣètànjẹ ń ba ẹ̀rí àwọn olùpèsè tí a jẹ́rìísí tí a sì bọ̀wọ̀fún jẹ́.

.

**1-877-87-FRAUD**
**877-873-7283**

**www.omig.ny.gov**
**www.omig.ny.gov/medicaid-fraud/file-allegation**

NEW YORK STATE OF OPPORTUNITY. | Office of the Medicaid Inspector General

NEW YORK STATE OF OPPORTUNITY. | Office of the Medicaid Inspector General

# Àfisùn Ìtànjẹ Medicaid ní Ìpínlẹ̀ New York



**Kathy Hochul**
**Gómìnà**

**Frank T. Walsh, Jr.**
**Ọ̀gá Àgbà Fìdíẹ ti Medicaid**

# Ṣèrànwọ́ Ìdẹ́kun Ìtànjẹ Medicaid

## Àwọn àpẹrẹ ìtànjẹ olùpèsè:

- Gígba àsanpadà fún aláìsàn tí a darí
- Gbéwiri
- Síso àwọn iṣẹ́ tí kò wúlò fún ìlera rárá
- Ìdíyelé iṣẹ́ kannáa ní ọ̀pọ̀ ìgbà
- Ìdíyelé isẹ́ tí a kò pèsè



## Àwọn àpẹrẹ ìtànjẹ olùgbà:

- Ìrajà dókítà tàbí àbẹ̀wò yàrá pàjáwìrì tí ń wá àpọ̀jù àwọn ògùn ìdarí
- Àìjábọ̀ ilé-iṣẹ́ adójútòfò ìlera míràn
- Yíyí ìwé ìdíyelé tàbí ìwé ìsanwó
- Fífa ìwé ìbéèrè kalẹ̀ fún mọ̀lẹ́bí
- Jíjábọ̀ owó àpawọlé tó kéré sí iye tí o ń gbà láti le yẹ
- Gbígba ẹ̀bùn tàbí kóríyá ní ìpàrọ̀ fún lílo olùpèsè pàtó kan
- Yíyá ẹlòmíràn ní káàdì Medicaid kan

## Bí o ti le gbógunti ìtànjẹ:

- Bèrè àwọn ìbéèrè lọ́wọ́ dókítà rẹ. Ṣàrídájú wípé o mọ̀ o sì lóye àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ṣe.
- Jẹ́ kó yé ọ. Tọ́jú àwọn àkọsílẹ̀ iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera rẹ, kí o sì ṣàyẹ̀wò gbogbo gbólóhùn ìlera tí o gbà. Ṣé déètì iṣẹ́ náà tọ̀nà bí? Ṣé o gba àwọn iṣẹ́ tí a díyelé bí?
- Tọ́jú káàdì Ìdánimọ̀ Medicaid rẹ bó ti yẹ káàdì àwìn. Máṣe fún ẹnikẹ́ni ní nọ́mbà ètò rẹ sí ìlẹ̀kùn-sí, ìlẹ̀kùn àwọn atajà, ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àwọn agbẹ́jọ́rò tàbí lórí Ayélujára.
- Ṣọ́ra fún ohun "ọ̀fẹ́" ti ìtọ́jú ìlera àwọn iṣẹ́, àyẹ̀wò tàbí ìtọ́jú tó máa ń jẹ́ ọ̀nà ìtànjẹ.
- Fi ìtànjẹ sùn. Kàn sí:

**Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gá Àgbà ti Medicaid**
Àjọ Ìfisùn Ìtànjẹ Medicaid
800 North Pearl Street
Albany, NY 12204

**877-87-FRAUD (877-873-7283)**

Orí ayélujára: **www.omig.ny.gov**

www.omig.ny.gov/medicaid-fraud/file-allegation

## Àwọn olùsọ̀rọ̀ síta ti iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera ni òfin ń dáàbo bò

**Tí o bá ń ṣiṣẹ́ ní ibi ìtọ́jú ìlera tí o sì jábọ̀ ìtànjẹ tàbí àṣìlò Medicaid, agbanisíṣẹ́ rẹ ni a kò gbà láàyè láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó lòdì sí ọ.**

**Àwọn agbanisíṣẹ́ tó bá gbẹ̀sàn lára àwọn òṣìṣẹ́ yóò san owó ìtaràn àti a le ni kí o sanwó sísọnù, àwọn ànfàní, àti owó iṣẹ́ òfin. Àwọn òṣìṣẹ́ tí a lé ni a le gbà padà.**

**Kàn sí Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ OMIG ní:**

**1-877-87-FRAUD (877-873-7283)**

**tàbí ní: www.omig.ny.gov**



NEW YORK STATE OF OPPORTUNITY. Office of the Medicaid Inspector General